# Ọkunrin kan ti o lọ fọ'le wẹwọn ọdun mẹta

IBADAN.

Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi ni Ogbẹni R. W. Rhodes-Vivour, Adajọ Kotu kekere kan ni Ibadan sọ ọkunrin kan ti o nwaṣẹ, Samuel Nwafe, ẹni ọdun mejidilọgbọn si ẹwọn ọdun mẹta fun ẹsun ile-fifọ, ole-jija ati gbigba ẹru ole dani ni alẹ aisun mọju ọdun titun ti o kọja yi.

Ogbẹni M. Aina, Ọlọpa olokun meji ti o ba ọdaran na ṣẹjọ sọ ni Kotu pe, Iye ẹru Dọkita S. H. Volsee ti ọdaran na ji ko ninu ile rẹ ni deede agogo mọkanla oru ni Ile-iwe Gigajulọ Ibadan jẹ oni pọnun mejilelọgorin ṣile mẹjọ-abọ (£82. 8s. 6d.).

Ọdaran na gba pe, on jẹbi ṣugbọn o ni ẹnikan ti o njẹ Matthew Oyekwere ni o gbe e le on lọwọ nigbati on lọ ri arakunrin on kan D. . Ezara nibẹ lati ba on wa iṣẹ, on ko tilẹ mọ ile ti arakunrin na ngbe, awọn ọlọpa si fi oluwarẹ na ṣe awati.

# Obirin kan bi Ibẹrin

IBADAN.

Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi ni obirin kan, Iyaafin Hannah Okoji ti o ngbe Opopo Race Course ni Ibadan, ti iṣe iyawo awakọ Reluwe kan, bi ọmọ mẹrin—ọkunrin meji, obirin meji lẹkanṣoṣo si Ile-igbẹbi ti o wa ni Ile-iwe-Gigajulọ (University College) Ibadan, awọn ọmọ mẹrẹrin na si wa ni alafia dada.

Iyaafin Okoji ti bi ọmọ mẹrin silẹ ṣiwaju awọn Ibẹrin yi, on si ni ẹni akọkọ ti o bimọ si Ile-Igbẹbi yi. Dọkita Lawson ti i ṣe Oga ile-igbẹbi na sọ fun oniwe Irohin wa pe, Ibẹrin ṣọwọn l'ọmọ pupọ, o ni agbarakaka ni nwọn fi nri oni-'bẹrin larin ogun-ọkẹ aboyun (400,000 pregnancies) ni ilu Oyinbo.

# Kọkọrọ Alagbalugbu

(LATI OJU EWE KẸJỌ)

Nigbati o ri pe o de itosi on tan, o ki ṣẹkẹrẹ rẹ mọlẹ o bẹrẹ si lu ilu gẹgẹbi iṣe rẹ, ikan kojọ ọkan egede ni on pe, Ẹkun ti o ti mura ija, ju ogọ nu o bẹrẹ si i ju iru rẹ bi aja si Ọdẹ Oniṣẹkẹrẹ. Gbogbo awọn ẹranko yoku ti doju bolẹ nitori kosi ẹniti o le wo o loju. Nigbati o sunmọ Ọdẹ Oniṣẹkẹrẹ o gbe kumọ rẹ soke o lu u mọ ọ lori o si ku finrinfinrin.

### ARA ỌDẸ AMUJẸ KO GBA A

Ibanujẹ dori Ọdẹ Amujẹ kodo, nigbati o ri pe Ọdẹ Oniṣẹkẹrẹ ti pa iyawo on, o pe ẹgbọn rẹ, o ni "Ẹgbọn mi ọwọn iwọ ni oluranlọwọ mi lati igba ewe mi wa, nko mọ ẹlomiran li ẹgbọn afi iwọ nikanṣoṣo, iwọ li o fẹ iyawo fun mi, iwọ gan an li o si pa a. Nisisiyi nko le nikan dagbe, ọmọ mi ko si ti i gbogan to lati da jẹ, emi ati ọmọ mi yio maa lo sibiti Oluwa ba dari mi si." Oluwa Alanu ko sọ ipade wa pẹlu omi oju ni o fi dagbere fun ẹgbọn rẹ pe odigbọṣe.

Bi o ti fẹ ma a lọ ni ẹgbọn rẹ da a pada o ni, "Aburo mi Ọdẹ Amujẹ, mo gbọ ọrọ rẹ ni agbọye, ki iṣe ifẹ inu mi lati pa iyawo rẹ, ẹṣẹ ipania ni o gaju lọ ni ode isisiyi. Ẹniti o ba si pa enia pipa ni a o pa on na. Nisisiyi bi iwọ ati ọmọ rẹ yio ti mu irin-ajo nyin pọn yi, ile aiye kun fun iya, ẹgbin, iṣẹ ati idarudapo, o si tun nfẹ suuru gidigidi nitoripe onisuru lo l'aiye. Ma a toju ọmọ rẹ dada, ma jẹki ebi pa a tabi orugbẹ gbẹ ẹ, nitoripe on ni yio dele de ọ lẹhin ọla.

O ni sunmọhin aburo mi, o si sunmọ ọ, o ni, "Lati oni lọ ẹda alaiye kan ko ni lagbara lori rẹ mọ, kosi ẹranko igbo ti o le doju ija kọ ọ, alujannu oke ati isalẹ yio ma a ri ọ sa ni. Ma a lọ ni alafia, ipade wa yio dun bi oyin, bi Oluwa ba wi bẹ ẹ. Ṣugbọn ohun kan ni ngo tun sọ fun ọ, ibikibi ti o ba ti ba ijamba pade ti agbara rẹ ko ba ka a pe emi Ọdẹ Onisẹkẹrẹ lẹsẹkẹsẹ, ngo si yọ si ọ fun iranlọwọ". Bayi ni awọn mejeji fa ọmọ wọn dani li ọkọọkan.

**Akiyesi:—Lọṣẹ to ...mbọ** lagbara Odua. Ẹ o ma ka bi bi Ọdẹ Amujẹ ti ṣe ba ijamba pade. O digba kan na o, oju ko fẹra ku o.

*Ẹ ma a ka Iwe*
*IROHIN YORUBA*
*nigbagbogbo fun*
*irohin aladun*





**Gbigbona tabi Tutu**
**Gẹgẹbi IWỌ ba ti fẹ**



NIHIN NI
ILERA
MI
ATATA
WA—






*L'arọ*

**Andrews**



Bi o ti wu ki o le rẹ ẹ to ki ara rẹ wẹsi to nigbati o ba ji, mimu ife Andrews Liver Salt kan ti o nta wọnin-wọnin l'arọ yio fi ọkan rẹ balẹ fun igbadun ilera ọjọ. Sa ti bu ẹkun ṣibi kekere meji sinu ẹkun omi tombila kan, yio ru ṣuṣu, sa gbe mu bẹ ẹ.

Andrews tutu, o dun, o si ngmu ẹnu ya akọtun. O nfọ ẹnu ati ahọn mọ, o ngmu inu walẹ, o nfun ẹdọ-ki lagbara. Lakotan, Andrews a ma a rọra ko gbogbo idọti inu jade ṣugbọn pẹlu irọrun ni, o njẹki Inu Mọ dada, o si nfun ni ni ilera dada.

Fun ararọ ti o ba ri i pe, ara rẹ "ko ya" ma a jẹki agolo Andrews kan wa ni arọwọto ẹ nigbagbogbo.

O DUN-LẸNU
O nta Wọnin-Wọnin . . . O Ntẹjẹṣẹ !
Agolo Tọlọmọde—3s. 6d. Agolo Imudani—2s. 3d.
Agolo ka lo o wo—1s. 6d.

